àwọn MUFARRIDUUN ti ṣíwájú

Láti ọdọ Abu Huraira- ki Ọlọhun yọnu si i- o sọ pé: Ojisẹ Ọlọhun- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- n rin loju ọna Makkah, ni o ba kọjá nibi oke kan ti wọn n pe e ni Jumdaan, o sọ pe: "Ẹ maa rin lọ, Jumdaan nìyí, àwọn MUFARRIDUUN ti ṣíwájú" wọn sọ pe: Awọn wo ni MUFARRIDUUN irẹ ojisẹ Ọlọhun? O sọ pe: Awọn ni àwọn oluranti Ọlọhun lọkunrin lọpọlọpọ ati awọn oluranti Ọlọhun lobinrin".

[O ni alaafia] [Muslim gba a wa]

Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- ṣàlàyé ipo awọn oluranti Ọlọhun lọpọlọpọ, pe wọn ti dá wà wọ́n si ti ṣáájú àwọn ti wọn yàtọ si wọn pẹlu pe ọwọ wọn tẹ awọn ipo ti o ga julọ ninu alujanna onidẹra, o wa fi wọn we oke Jumdaan ti o da wa laarin awọn oke yókù.

http://sunnah.global/hadeeth/yo/show/3719